



OLOYE S. Ade. Ojo (ni apa osi); Alafin Ọyọ, Ọba Lam'di Adeyẹmi Kẹta; Ogbẹni Thomas shropshire nworan nibi idije ere ẹlẹṣin ni Ibadan laipẹ yi. Ni apa ọ'un, diẹ ninu awọn ẹlẹṣin ti gb'ode.



# AJỌṢE WA KO NI BAJẸ





AWORAN apa osi ni oke nṣe ifihan olukọni kan ni ile eko giga, Lagelu ni Ibadan. Ogbẹni Adebayọ Adetọna pẹlu iyawo rẹ titun Omidan Olufunmilayọ Fọlarin lẹba akara aladun "onile-gogoro", nibi apejẹ ase igbeyawo wọn Ninu aworan apa osi, Omidan Taiwo Aderinọla Akofiranmi nfi owo si iwe igbeyawo pẹlu bale re. Ogbẹni J. O. Ọlọpade ni ilu Eko Ninu aworan apa otun ni oke Ọgbẹni S. O. Akele (ti o na ọwọ siwaju), Oga ibi iṣẹ ọgbin ọpẹ elepo-pupa ni Ewohimi, ni Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun nṣe alaye kikun fun awọn alejo pataki lati Ipinle Ila Orun Oke Oya Alhaji Muhammadu Mai (ni apa osi) ẹniti iṣe alakoso iṣe agbe Ipinle re; pelu won ni awon osise ibi ile iṣẹ agbẹ ti Ipinle Agbedemeji Iwọ Orun.



# Igbeyawo n'ilẹ Yoruba

(Bẹrẹ l'oju ewe kẹrin)

Bi o ba ti fe bere ọbẹ sise ni yio fọ awo, ti yio da ina, ti awọn ọmọde ile yio baa lọ efọ ọọyọ tabi isapa, ati oniruru nkan elo ọbẹ.

Ọbẹ sise je idanwo keji ti awọn ebi oko obinrin maa nse fun iyawo aburo tabi ẹgbọn wọn nitoripe wọn yio maa wo boya ọbẹ ti o ba se yio dun tabi bẹkọ Ti iyawo ko ba mọ ọbẹ sise daradara itiju l'o maa jasi fun Nwọn a maa pee ni orisirisi oruko Bi iyọ ba ja ọbẹ rẹ, oran ni Bi iyọ ko ba to, ijongbon ni. Bi iru ba poju tulasi ni Bi epo ba poju tabi ti ko ba to, ija ni Nwọn a le gongo de iyawo lati bu u pe ko mọ ọbẹ sise Nwọn le sọ pe ata poju tabi alubosa ko to: Iru alebu iyawo yi lee da ija s'arin t'ọkọ-t'aya na.

### IYAALE

Sugbọn bi o ba je iyawo ti ọkọ re ti ni iyaale tẹlẹ ri, iru eyi ko ni ri bẹẹ. Iyawo yio maa se iṣẹ pẹpẹpẹ miran fun iyaale re nigbati iyaale funra re yio maa se ọbẹ. Ni igba miran, iyawo titun lee duro ti iyaale yi lati fi oju si bi iyaale rẹ se nwa onjẹ ọkọ wọn:

Lẹhin igbeyawo, iyawo titun yio maa ba ọkọ rẹ lọ si oko re nitori iṣẹ agbẹ ni o poju ni iṣẹ okunrin ni aiye atijọ, afi awọn alagbẹde tabi ijoye ni kii kuro ni ile Iyawo yio tẹle ọkọ rẹ lọ si oko rẹ lati lọ baa siṣẹ Ti nwọn ba nlọ sinu oko, ọkọ yio wa lẹhin, iyawo yio wa niwaju pẹlu agbọn tabi ohun elo irẹru ni ori rẹ:

### ISE OKO

Bi ebi ọkọ re tabi aburo ọkọ rẹ tabi iya ọkọ rẹ ba mba won lọ si oko iyawo ni o nilati ru agbọn won tabi oṣuka tabi okun ti nwọn fẹ fi di igi tabi ohunkohun ti nwon ba mu dani fun siṣẹ nkan l'oko

Nigbati nwọn ba de oko, iyawo yio ya si ahere lati dana onjẹ fun ọkọ rẹ Lẹhin eyi ni yio gbe onje lọ baa ninu oko tabi ki o pee lati wa jẹun Igba miran wa ti o jẹ wipe onjẹ ki iṣe sise, papa ni akoko idako titun. O le jẹ wipe ki nwọn fi iṣu s'ina — gẹgẹ bi ewura tabi koko, ti won yio fi ikẹtẹ epo jẹ.

Bi akoko ba ti ri ni onjẹ maa nri l'oko: Gẹgẹ bi apere, ni akoko ojo ti awọn ewebẹ wa daradara, efo elegede, yanrin tẹtẹ, ebolo, ngbologi amunututu soko-yokolo ajẹfawo ati orisirisi ẹfọ wa ni tutu yoyo ti iyawo le fi se ọbẹ aladun fun jijẹ iyan, tabi ọka gbigbona tabi amala ati ẹkọ

Ni akoko ẹrun awọn nkan wonyi a maa wọn diẹdiẹ, onjẹ a si yatọ diẹ bakanna O le je ọbẹ gbẹgiri tabi ilasa ni iyawo maa se fun jijẹ awọn nkan wonyi

Ni akoko wọnyi, ireti awọn enia ni pe iyawo yio ti l'oyun sinu Inu ọkọ iyawo maa ndun pupọ-pupọ nigbati o ba ri pe iyawo on ti loyun sinu nitoripe eyi ni idi pataki ti ọkọ fi nfẹ aya rẹ:

Loni yi, aiye ti d'aiye oyinbo Asa Igbeyawo ti yatọ: Diẹ ninu awọn iyawo wa ni o mọ ona oko ọkọ rẹ afi igba l'okan ti nwọn ba lọ si oko lo mu onjẹ Igbesi aiye rere iyawo n'ile ọkọ re wa lọwọ iwa re nitori iwa rere l'eso enia



# IYAWO DUN LỌṢINGIN

ERIN ayọ igbeyawo ko soro mọ Gbogbo "agbado" funfun eyin ni a fi nrin ... Iru ẹrin na ni a nwo ninu aworan oke yi, eyiti a nṣe ifihan Ogbeni Bisi Ajibade, ni kete lẹhin isin idapọ mimọ re pelu Omidan Ebun Alat ... ni ilu Eko. Ninu aworan apa osi, awọn olukọni t'ọkọ-t'aya mejeji di ọbẹ kanṣoṣo mu, lati ge akara igbeyawo wọn, Ogbeni Isaac Olufẹmi Adelotaju ati Josephine Temitọpẹ Odusọwọ ṣe alaye pe awọn se eyi nitoripe nipa idapọ mimọ, awọn ti di ara kanṣoṣo ti ẹnikeni ko gbọdọ ya ni ipa mọ:

